# IPARUN SODOMU ATI GOMORRA

**Gẹnẹsisi 18:20-33; 19:1-29**

**ẸKỌ 10 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Oluwa mọ̀ bi ã ti íyọ awọn ẹni ìwa-bi-Ọlọrun kuro ninu idanwo, ati bi ã ti ipa awọn alaiṣõtọ ti a njẹ niya mọ dè ọjọ idajọ" (2 Peteru 2:9).**

**I Adura Agbayọri**

1 Ọlọrun gbọ́ igbe Sodomu ati Gomorra nitori awọn ẹ̀ṣẹ wọn ti o papọ̀ jù, Gẹnẹsisi 18:20, 21

2 Abrahamu bẹ̀bẹ̀ lọdọ Ọlọrun lati dá Sodomu si kuro ninu iparun bi olododo mẹwaa ba wà ninu ilu naa, Gẹnẹsisi 18:22-33; Ẹksodu 32:30-32; 2 Samuẹli 24:16, 17; Romu 9:1-3; 10:1

3 Ọlọrun dahun adura Abrahamu, Gẹnẹsisi 19:29

**II Igbala Lọti**

1 Lọti fi ayọ̀ gba awọn angẹli Ọlọrun naa si ile rẹ̀ nigba ti wọn dé Sodomu, Gẹnẹsisi 19:1-3; Heberu 13:1, 2; Luku 24:28-31

2 Awọn eniyan ilu yii n wá ọna lati ṣe ibi si awọn alejo Lọti ṣugbọn a fi agbara ti o ju ti ẹ̀dá lọ dí wọn lọwọ, Gẹnẹsisi 19:4-11; 2 Awọn Ọba 6:18

3 A fi ikilọ Lọti fun awọn ara ile rẹ̀ ṣe ẹlẹya, Gẹnẹsisi 19:12-14; 2 Peteru 3:3, 4; Matteu 24:42-51; 1 Tẹssalonika 4:8

4 Igbala Lọti ati awọn ọmọbinrin rẹ meji lati ọwọ Ọlọrun wá jẹ́ apẹẹrẹ idasilẹ awọn eniyan mimọ́ Ọlọrun nigba Ipalarada kuro ninu Ipọnju Nla, Gẹnẹsisi 19:15-17; Matteu 24:40, 41; 1 Tẹssalonika 5:1-9

**III Ibinu Ọlọrun**

1 Lọti bẹ̀bẹ̀ a si fun un ni ayè lati sá si ilu kekere kan ni pẹtẹlẹ naa, Gẹnẹsisi 19:18-23

2 A dá idajọ duro, titi awọn olododo fi wà lai lewu, Gẹnẹsisi 19:22; Isaiah 26:20

3 Ọlọrun pa awọn ilú pẹtẹlẹ run – ijiya yii jẹ́ apẹẹrẹ gbogbo idajọ Ọlọrun lori ẹ̀ṣẹ ati awọn ẹlẹ́ṣẹ, Gẹnẹsisi 19:24-29; 2 Peteru 2:4-10; Juda 5-7, 15; Ifihan 6:17

4 Aya Lọti boju wo ẹ̀yìn o si di ọwọ̀n iyọ̀, Gẹnẹsisi 19:17, 26; Luku 17:28-37

## ALAYE

**Agbára Adura**

Ododo Abrahamu ni o mu ki Ọlọrun sọ fun un nipa iparun ti yoo wá sori Sodomu ati Gomorra lai pẹ. Ni Sodomu ni ọmọ arakunrin Abrahamu ọkunrin ti a n pè ni Lọti n gbé. Iwa buburu ti o ba ni lẹru ti awọn ará ilu pẹtẹlẹ yii hù ti mu Ọlọrun binu to bẹẹ gẹẹ ti O fẹ pa wọn run kuro lori ilẹ ayé. (Wo Esekiẹli 16:49, 50). Iru iroyin yii dá Abrahamu niji, lẹsẹkẹsẹ ni o si bẹrẹ si i bẹ̀bẹ̀ lọdọ Oluwa lati dá ilu Sodomu si. Oluwa gbà lati dá ilu naa si bi a ba ri aadọta olododo ninu rẹ̀. A gbọdọ ti sọ fun Abrahamu nipa iwà buburu awọn ara ilu yii nitori o tẹra mọ́ ẹ̀bẹ̀ fun ilu naa titi Oluwa fi gbà pe a o dá ilu naa si bi a ba ri olododo mẹwaa ninu rẹ̀.

O gbọdọ jẹ ohun iwuri nla nla fun gbogbo eniyan ti wọn n gbadura si Ọlọrun alaaye lati mọ̀ pe, nigbakuugba ni a le fa idajọ Ọlọrun sẹyin, tabi ki a tilẹ dá a duro paapaa, nipa adura agbayọri olododo eniyan Ọlọrun kan. "Iṣẹ ti adura olododo nṣe li agbara pupọ" (Jakọbu 5:16). Ọlọrun nikan ni o mọ iye awọn ọkunrin ati awọn obinrin, lati ọpọlọpọ ọgọrun ọdun sẹyin, ti a ti dá silẹ kuro lọwọ ikú ati irora ọrun apaadi, nitori adura ẹni kan ti o fẹran wọn to bẹẹ ti o takú ti Ọlọrun lati dá ẹmi wọn ati ọkàn wọn sí titi wọn yoo fi ronupiwada awọn ẹ̀ṣẹ wọn. O ṣe ni laanu pe, ni Sodomu ati awọn ilu pẹtẹlẹ, bi o tilẹ jẹ pe Abrahamu bẹ̀bẹ̀, a kò ri olododo mẹwaa paapaa ni Sodomu; nitori naa irunu idajọ Ọlọrun wá sori wọn.

**Awọn Iranṣẹ ti o fun Ni ni Anfaani lati Yàn**

Oluwa rán awọn angẹli meji lọ si Sodomu, boya, lati mọ̀ iduro Lọti ninu ilu Sodomu ati lati yọ ọ kuro ninu iparun ti n bọ̀ wá. Lọti, nitori o wà ni ẹnu bode ilu naa, woye pe wọn jẹ́ alejo, o si pè wọn lati wá wọ̀ sọdọ oun. O dara fun Lọti pe o fi irú inu rere ẹni iwa-bi-Ọlọrun bẹẹ hàn fun awọn alejo wọnyii. Oun ko mọ̀

pe angẹli Ọlọrun ni wọn i ṣe, kò si mọ nipa iparun ti o n bọ̀ wá sori ilu naa, ati pe wọn wà nibẹ nitori eyi; ṣugbọn inú rere ati alejo ṣiṣe rẹ̀ fun un ni erè pupọ ni alẹ́ ọjọ naa.

Lai ṣiyemeji, ẹni ti o kọ Episteli si awọn Heberu ni ohun ti o ṣẹlẹ yii ni ọkàn nigba ti o sọ fun awọn Heberu Onigbagbọ́ lati jẹ́ "Ki ifẹ ará ki o wà titi," ati pe ki wọn má ṣe gbagbe lati maa ṣe alejo, nitori nipa bẹẹ ni awọn ẹlomiran ṣe awọn angẹli ni alejo lai mọ (Heberu 13:1, 2). Iwe Mimọ́ sọ pe nitori adura Abrahamu ni a ṣe gba Lọti silẹ kuro ninu iparun Sodomu ati Gomorra (Wo Gẹnẹsisi 19:29). Ṣugbọn bi Lọti ba ti ṣe alai ka awọn angẹli Ọlọrun wọnyii si, ki o si kọ̀, gẹgẹ bi awọn ana Lọti ti ṣe, lati feti si ikilọ lati sá asalà, oun i ba si ṣegbé bi o tilẹ jẹ pe a fun un ni àye lati sá asalà.

**Ọna Asala**

Bi o tilẹ jẹ pe nigbakuugba ni adura awọn olododo yoo dí idajọ Ọlọrun ti o dáju lọwọ lati ṣẹ fun ọpọ ọdun, ọjọ ibẹwo yoo de dandan nikẹyin. Bi a ba ṣe alai ka ọna ati salà si, nigba naa ko si ohun ti o kù bi ko ṣe lati jiya ibinu ododo Ọlọrun. Ọpọ awọn ọkunrin ati awọn obinrin ni o wà ti a ti tọ́ labẹ itọni awọn baba ati awọn iya ẹni iwa-bi-Ọlọrun, ti wọn si ti di agbalagba lai wá igbalà Kristi ti a ti fi kọ́ wọn lati igba èwe wọn wá. Nigba pupọ ni wọn yoo sọ pe adura awọn obi wọn ti tó, ati pe yoo jẹ́ fun wọn. Kò si adura obi ti o le gbà ẹnikẹni là. Awọn adura wọnni le fi agbara mu eniyan lọ sinu ipinnu fun wiwá igbalà Ọlọrun tabi lilodi si igbalà Ọlọrun; awọn adura wọnni le jẹ ki ọjọ iṣiro naa sún siwaju, tabi dá a duro fun saa kan; awọn adura wọnni yoo mi ọwọ́ Ọlọrun gẹgẹ bi adura Abrahamu fun ọmọ arakunrin rẹ̀ ọkunrin, Lọti ti ṣe; ṣugbọn Lọti i bá sọ ẹmi ati ọkàn rẹ̀ nù, bi o ba kọ̀ lati tẹle awọn angẹli Ọlọrun ti wọn titori ti rẹ̀ wá.

Ẹjẹ Kristi ti o n wẹ awọn ẹ̀ṣẹ ọkàn kuro, ni ọna ti Ọlọrun pese silẹ fun araye lati yọ kuro ninu awọn idajọ ti Ọlọrun yoo rán wá si ayé lai pẹ. "Nitori Ọlọrun yàn wa ki i ṣe si ibinu, ṣugbọn si ati ni igbala nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa" (1 Tẹssalonika 5:9). Sisá àsalà ti Noa sala kuro ninu Ikun-omi, ninu ọkọ̀ ti o kàn nipa itọni ati ifimọna Oluwa; igbala awọn ọmọ Israẹli kuro ni Egipti, ati ipamọ́ wọn kuro ninu awọn ajakalẹ-arun ati ikú ti o wá sori Egipti; ati idasilẹ Lọti kuro ni Sodomu – gbogbo eyi jẹ́ apẹẹrẹ igbalà awọn olododo kuro ninu idajọ ikẹyin ti yoo wá sori ayé ati ẹ̀ṣẹ gbogbo. Jesu kilọ fun awọn olugbọ Rẹ̀ nitori nnkan wọnyii, O sọ fun wọn nipa iwa buburu awọn eniyan igba ayé Noa ati Lọti, O si ṣeleri iru opin bẹẹ bi wọn kò ba ronupiwada awọn ẹ̀ṣẹ wọn.

Ni opin ohun gbogbo, Jesu yoo pada, yoo si gba awọn eniyan ti Rẹ̀ sọdọ ara Rẹ̀. A o ji awọn okú olododo si iye ainipẹkun, a o si gba awọn eniyan mimọ́ ti wọn ṣi wà laaye soke pẹlu wọn lati pade Oluwa ni sanma; ṣugbọn awọn eniyan buburu ti o ti kú, ki yoo wà laaye ni akoko ijọba ẹgbẹrun ọdun (Ka Ifihan 20:5, 6).

**Ranti Aya Lọti**

Lọti sá asala kuro ni Sodomu pẹlu ẹmi rẹ̀, ṣugbọn o ni lati fi gbogbo ohun ini ayé rẹ̀ silẹ. Onigbagbọ́ tootọ́ ninu Kristi ni iṣura ọkàn rẹ̀ nibi ti awọn olè ko le runlẹ ki wọn si jale, ati nibi ti kokoro ati ipaara kò le ba a jẹ (Ka Matteu 6:20).

Bi o tilẹ jẹ pe Lọti jẹ́ olododo, o ni ohun ini rẹ̀ ni Sodomu; wọn si parun pẹlu ilu naa. Abrahamu, ẹni iwa-bi-Ọlorun, ti o jẹ́ arakunrin baba rẹ̀, ti yan ọ̀na ti o dara jù, o si ti fi awọn iṣura rẹ̀ pamọ si ọdọ Oluwa. Abrahamu ti yan awọn ohun ti Ọlọrun, ohun ti ẹmi fun iṣura rẹ̀, sibẹ wọn jẹ́ ini rẹ titi di oni-oloni (Wo Johannu 4:36). O n ká erè si iyè ainipẹkun, nigba ti o jẹ pe a fi iná run iṣẹ Lọti, pẹlu ipá paapaa ni oun tikara rẹ fi yọ kuro ninu iparun (Ka 1 Kọrinti 3:10-15).

Awọn angẹli naa kilọ fun Lọti ati ẹbi rẹ̀ lati sá kuro ni pẹtẹlẹ, ati pe ki wọn ma si ṣe wo ẹyin. Bi aya Lọti ti n salọ, o duro lati boju wo ẹyin wo ilu naa lati ibi ti wọn ti sá kuro, o si di ọwọ̀n iyọ̀. Iṣura rẹ wà ninu ilu naa sibẹ, nigba ti oun ko si dá ara rẹ̀ lẹkun lati ma wo ẹyin, idajọ Ọlọrun kọlu u. "Nibiti iṣura yin bá gbé wà, nibẹ̀ li ọkàn nyin yio gbé wà pẹlu" (Matteu 6:21).

Nigba ti a bá ti gba eniyan kan kuro ninu ẹ̀ṣẹ lẹẹkan, ko gbọdọ tun "boju wo ẹyin" si igbesi-ayé atijọ, nitori ṣiṣe bẹẹ yoo jẹ́ ẹ̀ṣẹ. Jesu rọra kilọ fun awọn olugbọ́ Rẹ̀ nipa idajọ ti yoo wá sori ayé, lẹyin naa ni o fi opin aya Lọti ti o boju wo ẹyin, ṣe ikilọ fun awọn wọnni ti yoo fi iwa omugọ̀ duro de ajálù, ti wọn kò si ni jẹ́ ki ipè wọn lati ọrun ati yiyan wọn daju. Ni akoko miiran, Jesu gba awọn olugbọ́ Rẹ̀ niyanju pe, "kò si ẹni, ti o fi ọwọ́ rẹ̀ le ohunelo itulẹ, ti o si wò ẹhin, ti o yẹ fun ijọba Ọlọrun" (Luku 9:62). Bakan naa ni Peteru kilọ nipa ewu ti o wà ni pipada boju wo igbesi-ayé ẹ̀ṣẹ atijọ. "Nitori lẹhin ti nwọn ba ti yọ tan kuro ninu ẽri aiye, nipa mimọ̀ Oluwa ati Olugbala wa Jesu Kristi, bi nwọn ba si tun fi ara kó o, ti a si ṣẹgun wọn, igbẹhin wọn a

buru jù ti iṣaju lọ. Nitori ìba san fun wọn, ki nwọn ki o má mọ̀ ọ̀na ododo, jù lẹhin ti wọn mọ̀ ọ tan, ki nwọn ki o yipada kuro ninu ofin mimọ́ ti a fi fun wọn" (2 Peteru 2:20, 21). Bayii ni aya Lọti ti o boju wo ẹyin wo Sodomu sọ anfaani ti o ni lati sá àsálà nù, o si fi ẹmi ati ọkàn rẹ̀ di i, lati igba naa ni o si ti di apẹẹrẹ iwa were ti o wà ninu ifasẹyin.

**"Ranti aya Lọti."**

**AWỌN IBEERE**

1 Bawo ni Abrahamu ṣe gbọ́ pe a o pa Sodomu ati Gomorra run?

2 Ki ni ṣe ti Abrahamu n ṣe aniyan lori Lọti, ọmọ arakunrin rẹ̀?

3 Ki ni ohun ti o ṣe lati ri i pe Lọti wà ni ailewu?

4 Ki ni iṣẹ awọn angẹli meji naa ni Sodomu?

5 Ki ni ṣe ti Lọti mu awọn angẹli meji wọnyii lọ si ilé pẹlu rẹ̀?

6 Ki ni ṣe ti awọn àna Lọti kò gba ikilọ Lọti gbọ?

7 Ni ọna wo ni yiyọ ti a yọ Lọti kuro ni Sodomu fi jẹ apẹẹrẹ Ipalaradà awọn eniyan mimọ́?

8 Ki ni ṣe ti aya Lọti boju wo ẹyin?

9 Ki ni ṣẹlẹ si aya Lọti?

10 Ki ni ṣe ti Jesu sọ fun awọn olugbọ́ Rẹ̀ lati ranti aya Lọti?